# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 560 FRIDAY, MARCH 20, 1964 (2D)

## Sule Lu Ęran Ęlęran Pa

EKO.— G ogbo ero ti o pejọ si ile ejọ kan ni Eko ni ijeta ti ṣe ọjọRu ti se ọjọ kejidinlogun oṣu yi lo ręrin ario do mi loju nigbati Ọgbęni A. Salawu nsọ fun ile ejọ na pe 'Emi ko mọ ohun ti ęran mi ṣe Sule ti o fi lu lalu pa toyun toyun inu rę' ę jọwọ ę ba mi bere lọwọ Sule?

Ọgbęni Salawu yi je ęlęri fun awọn Ọlọpa ninu ęsun ti nwọn fi sa Sule Shomade pe o lu ęran ewurę rę la lu pa.

Ninu ọrọ Salawu, o sọ pe ki Sule to ma"a lu ęr n ewurę na ti o lọ wa okun kan ti o fi di mọ ara opo ine ti o si na a titi o fi ku.

O tun sọ pe Sule ti wa ba ɛn ni Isọ on ni ọja Ọbun Eko ti o si ti gba owo lọwọ on nitoripe ęran ewurę on ti jẹ ę ni nkan ri.

O ni igbati Sule tun wa lekeji ti on ko fun un ni owo ni Sule ba binu lọ lu ęran pa.

Nwọn si nṣe ejọ na lọwọ, bi nwọn ba ti pari ejọ na si, ę o maa gbọ o.

# AWỌN ỌMỌ ILE–ĘKỌ GIGA O MAA SAN ỌGỌTA PỌNUN L'ỌDUN

ENUGUN:— Ni kutukutu owurọ ana ọjọ Ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni Irohin kan wa lati Ipinlę Ila Orun Naijiria wipe Ijọba Ipinlę na ti pa ni aṣę wipe gbogbo Ile-ękọ giga ti o wa ni Ipinlę na ko gbọdọ gba owo ti o ju ọgọta pọnun lọ lọwọ ọmọ Ile–ękọ kan fun ọdun kan.

Irohin na fi ye wa pe Dokita S. E Imoke Minista Alamojuto eto ękọ fun Ijọba Ipinlę Ila Orun Naijiria ni o mu aba na wa sinu Ile Igbimọ Aṣofin, ti nwọn nṣe ipade lọwọ bayi.

Ninu ọrọ rę, Dokita Imoke ṣe alaye wipe owo ti awon ti nbọ si Ile-ękọ giga nsan ti npọju ni ọdun kan, on si fę ki Ijọba ṣe ni ofin pe, ọgọta pọnun (£60) ni ki awọn ọmọ Ile-ękọ giga o ma a san.

Agbọ wipe, awọn ọmọ ile-ękọ giga miran nsan ọgọrin (£80) ninu ile-ęko wọn ni ọdun kan, Lęhinna ni nwọn a ra iwe, nwọn o da aṣọ ile iwe, bata, ati awọn nkan regbe-regbe miran.



**Dokita M. I. Okpara**

Lęhinna, Dokita Imoke tun ṣe alaye wipe gbogbo awọn Ile ękọ giga ti Ijọba Ipinlę na ba nṣe iranlọwọ Owo fun ko gbọdọ gba ju Ọgọta (£60) pọnun lọ ni Ọdun kan lọwọ Ọmọ Ile—ękọ kan.

Dokita na tun wa ṣe afikun ninu Ọrọ rę wipe, ninu Ọgọta pọnu (£60) ti awọn Ọmọ Ile ękọ giga na yio maa san, ninu rę ni Owo iwe, Owo aṣọ, Owo bata, Owo Ọja-Ọrun, Owo fila, Owo sokoto awọtęlę ati Owo bęliti wa.

Bakanna ęwę, ni Dọkita Imoke fi ye gbogbo awọn ọmọ ile Igbimọ na ni ana wipe gbogbo awọn Ile ękọ giga ti o wa ni Ipinlę na ti nwọn si ngba iranlọwọ-owo ko gbọdọ le awọn ọmọ Ile ękọ jade nitori owo Ile iwe.

Irohin fi ye wa wipe Ijọba Ipinlę na ti fi ofin si i, nwọn si tun pa a ni aṣę wipe lati ọjọ kini oṣu yi ni ofin na yio bęrę.

Lęhin ti nwọn ti ṣe ofin yi Ile ękọ kan ko gbọdọ le ọmọ Ile ękọ jade nitori aiko san owo Ile iwe.

Irohin fi ye wa wipe owo ti awọn Ile-ękọ giga miran ngba lọwọ awọn ọmọ Ile ękọ ko jęki ọpọlọpọ awọn obi o le ran ọmọ wọn jade iwe męwa, nitoripe ęru owo Ile iwe yi ti wọ awọn obi miran ni ọrun to bę gęe ti ẹniti o ni ọmọ męta fi nran ọkanṣoṣo lo si Ile–ękọ giga.

Ṣugbọn nigbati nwọn ti din owo ile iwe ku nisisiyi, a lero pe gbogbo awọn Obi ti nwọn ni ọmọ męrin tabi marun ti awọn ọmọ ti jade iwe męfa, yio le ma a ran awọn ọmọ wọn lọ si Ile-ękọ giga nisisiyi.

Ọpọlọpọ awọn Ile ękọ giga wọnyi, Ijọba le fun wọn ni owo ti nwọn fi kọ wọn, Ijọba lo ra ọpọlọpọ awọn ohun elo sinu awọn Ile iwe na, ti Ijọba si tun nsan owo-oṣu awọn olukọ wọn.

Ni ipari Dokita Imoke sọ pe ninu ọgọta pọnun yi ni awọn ọmọ ile-ękọ na o ma a san fun gbigbe inu ile–ękọ wọn, nitori ko si gbọdọ ma a lọ si ile wọn lo sun, ile-ękọ ni ki nwọn o ma a sun.

## Ọlọla Azikiwe Ni Olori Apapọ Ijọba

EKO:— Gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ lo ta ko Dọkita Elias, Minista Alamojuto eto iṣę Ofin ati idajọ fun Apapọ Ijọba Naijiria ninu Ile Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria nigbati Dọkita na mu aba kan wa pe ki Ijọba fi ọwọ si ofin kan eyiti yio fun Apapọ Ijọba Naijiria ni aṣę lati yan Igbimọ enia mejila, eyiti Alakoso Ijọba yio jẹ Alaga.

Dọkita na ṣe alaye pe, enia męfa lati Ile Igbimọ awọn agba oṣelu ati enia męfa ninu Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria.

Ṣugbọn awọn ọmọ Ile Igbimọ na tako aba yi fun nkan bi ogbọn iṣeju, pe, ko si eniti o fę yọ Dokita Azikiwe kuro ni aye rę, nitorina aba na ko waiye.

Awọn ọmọ Ile Igbimọ na ni awọn fę ki Dọkita Azikiwe wa ni aye rę.



Ọlọla Nnamdi Azikiwe

Awọn kan si da ri aba wipe ti wọn ba fę yan olori Ijọba miran ki o jẹ wipe, gbogbo awọn ara Ilu li ye ko dibo yan eniti nwọn ba fę, kio ma ṣi ṣe pe awọn ọmọ Ile Igbimọ nikan ni yio ma a dibo yan Olori Ijọba gęgębi eyi ti nwọn ṣe koja laipọ yi.

Ṣugbọn lęhin ọpọlọpọ ariyanjiyan nwọn sọ imọran na di Ofin.

# Ẹ Ronupiwada Ki Ẹ Si Gba Imọran

Lati ọwọ Alhaji Y. A. Disu

Awọn kan nbẹ, nwọn si kun orilẹ igun mẹrẹrin aiye. Nwọn fẹran lati maa ṣe ibi. Nwọn fẹran lati maa ṣe ogun ati lati maa sa tira lọna aidara si ọmọlakeji wọn, si ẹbi wọn, si ọrẹ wọn, si aladugbo wọn, ati si aya wọn.

Ẹni eṣu ni wọn. Nwọn ki gbero lati ṣe ohun ire si ẹni ti nwọn ba mọ. Ẹniti ko ba sọ wọn di oriṣa ki o si maa bọ wọn bi igbati awọn onişango ba nbọ ṣango.

Nwọn fẹki ọmọ enia ṣa maa kansara si wọn. Nwọn iba ṣe ibi, nwọn iba re ipa.

Ẹ ṣọra nyin lọdọ awọn ẹni ibi, a ni awọn ẹni Eṣu wọnyi. Ṣugbọn iwọnba niki ẹ bẹru wọn. Ọlọrun ni ki ẹsujada fun. Ọlọrun ni ki ẹpaiya Rẹ.



ALHAJI Y. A. DISU.

Ti Ọlọrun ni ki ẹ gbiyanju lati maa ṣe ni gbogbo igba yio si maa ṣe iranlọwọ Rẹ fun nyin ni igba gbogbo On ni a gbọdọ gbojule On ni o to gbojule, On ni o to fẹhinti.

ẸSAN NBỌ

Ẹ maa wo igbẹhin awọn abaniję ti nwọn ku ọfọ. Igbẹhin ni o dun oloku'ada. Awọn ti ibi wọn ko pe ni nwọn maa nsaba fẹ lati ma fẹ lati maa ṣe ika. Ika yio si ka wọn, Ọlọrun yi si mu wọn.

Ki awọn ṣikaṣika maa ṣe nṣo, esan nbọ. Ko si ẹda ti ọwọ Edumare ko ka Edumare ki i si gbe ibi fun alare ẹnyin oṣika abanijẹ kaakiri adugbo, ti ẹnfi oru sọsọkusọ, ti ẹkofi ooru sun, ti ẹ nfi ori boju ba awọn ẹgbọn nyin, awọn aburo nyin ati awọn ẹbi nyin kaakiri adugbo, ẹ lọ ronu piwada.

Ẹ ye leri tira mọ. Ẹ lọ mọ dajudaju pe, Ọlọrun ko fẹ opurọ abanijẹ Ọlọrun iaanu wọn.

Mo bẹ ẹnyin onikawe Irohin Imọlẹ jakejado ati gbogbo ẹniti mo mọ ati awọn ẹniti nko mọ ẹ jẹki a maa şişẹ ire, ki a maa rin irin ire, ki a si maa sọ ọrọ ire nigbogbo igba.

Ki ire baa le jẹ tiwa. Ire ni Ọlọrun nṣe fun awa ẹda, Ẹ jẹki awa na maa ṣe ire

"BABA ONISỌKUSỌ"

Ẹ jinna si baba onisọkusọ Ẹ jinna si opurọ ti o nfi oru sọ isọkusọ, ti osinfi ọsan sun. Ẹni eşu ni yẹn.

Ẹni ti o ba nṣe ire ti o si paiya Ọlọrun, oogun buburu ati tira asasi ko ni ran an.

Ẹnyin ẹni Ọlọrun, ẹ maa gbadura laarọ, lọsan, lalẹ ti loru ki Edumare ba a le ma a gbe nyin leke awọn abanijẹ, bi O ti ṣe gbe Anabi Muhanmed (kiikẹ ati atilẹhin Ọlọrun ma a baa titilailai. Amin.)

Mo sifẹ ki ẹma pe, ibajẹ enia ko disẹ Ọlọrun lọwọ

# Ọwọ Awọn Ọlọpa Tẹ Ẹniti Nrọ Owo

ENUGU:- Ọrọ di bi o lo ya fun mi bi awọn Ọlọpanu ti bẹlu ile asiri kan ti ọga ile iwe kan kọ sarin igbo, lati le ma lo fun iṣẹ agbẹdẹ ti yio ma rọ owo ayederu.

Ọrọ yi ṣẹlẹ ni ọjọ iṣegun ọsẹ ti o kọja yi nigbati irohin de ọdọ awọn Ọlọpa pe, ọga ile-iwe kan ti ilu Agbani ti kọ ile kan si arin igbo ti ko jinna si ile iwe nwọn ti o si saba ma lọ gbe ibẹ.

Gbogbo awọn olukọni ti o wa pẹlu rẹ ni ọrọ yi ma nya lẹnu pe awọn ko ri iru wa bayi ri.

Bi irohin yi ti de ọdọ awọn Ọlọpa ni wọn ba ta mọra ti nwọn şi lọ fara pamọ larin igbo ti o wa nitosi abule titun ti ọga ile-iwe yi kọ silẹ.

Bi asiko ti to fun ọga ileiwe yi lati bẹrẹ ise rẹ o ti ko gbogbo awọn irin iṣẹ rẹ silẹ ti o si gbiyanju lati ma se eto, ni awọn ọlọpanu ba ya a lu abule yi.

Bi ọga ile-iwe yi ti gbojusoke ti ori wọn lo ba fẹsẹ fẹ ti o si sare lasa fa eti tẹ Ṣugbọn awọn Ọlọpa yi ko jẹki o sare jina ti ọwọ nwọn fi te

Nwọn mu pada si abule rẹ, nibẹ ni wọn ti ri owo ayederu sile mẹdogun (15/-) sisi sisi tiko ti pari ti pọnun merilelogun sile mẹwa (£22 10s) ati tọrọ tọrọ pọnun meje (£7).

Awọn Ọlọpa tun ri awọn ẹrọ ti nfi rọ sisi sisi ati şile kọkan meji Ikede awọn ọlọpa fi ye wa wipe oti pẹ ti awọn alaba şişẹ po ọdaran ọga ile-Iwe yi ti fura sii ti nwọn ko tilẹ mọ aşiri ohun ti on ṣe larin Igbo yi rara.

Iwa yi jẹ ajeji si gbogbo awọn obi ti ọmọ wọn wa a nile iwe yi pupọ.

Nitoripe ti nwọn ba fẹ lati ri ọga ile-iwe yi, inira ni o njẹ fun wọn nigba-gbogbo ko tilẹ ba ẹnikankan damọran ki nwọn le mọ ohun ti o nṣe.

A gbọ wipe ọga ile iwe yi wa ni itimọle awọn ọlọpa bayi ti nwọn si tun ṣe iwadi lọwọ.

Bi nwọn ba ti nba ọrọ na lọ ẹo ma gbọ.

# Oniwasu Kan Fi £35 Tanran

ỌWO:- Oniwasu kan ti Ijọ Kerubu ati Serafu, Aposteli Augustus Adẹyẹri ni irohin fi ye wa pe ofi owo pọnun marundilogoji (£35) tanran fun ẹsun pe o ba igi obi ti owa ni adugbo Ishelu jẹ.

Onirohin wa fiye wa pe, Oniwasu yi jẹ adari sọsi Kerubu Serafu ati ile iwe ti awọn Ijọ rẹ pẹlu ile Iwe giga kan, ti anpe ni Adeyeri Grammar School.

Agbọ wipe awọn igi obi yi ti ole ni ogoji ni Oniwasu yi paşẹ ki wọn ke wọn lulẹ, lati le ṣe ọna lọ si ile iwe giga

Irohin na fi kun pe ọgbẹni Dafidi Ogunringbe ni o ni awọn igi obi na.

Ninu ọrọ rẹ ni'e ẹjọ Oniwasu na sọ pe ki ṣe on ni on paşẹ pe ki wọn ge igi obi na bi koşe igbimọ ti mojuto ilu Ọwọ (Ọwọ District Council).

O tun ṣe alaye pe awọn igbimọ na ni o fun on nilẹ ibi ti on kọ ile Iwe si ti wọn si ti paşẹ ki on kọ ile Iwe si ori ilẹ.

Adajọ kotu na sọ wipe on ko gba iru alaye ti Oniwasu yi ṣe, osi sọ pe ki o lọ san owo pọnnu marundinlogoji tabi ki o lọ si ẹwọn osu mẹfa.

Agbọ wipe Oniwasu ti san owo na ni oju ẹsẹ.

# Akiyesi

Ẹnikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba iba şe eyiti o ti ku ni tabi eyiti oşi wa laaiye tabi bi nwọn ti şe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Işẹdalẹ Yoruba, ki oluwarẹ kọ ọ sọwọ.

Ao si tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maşe jẹki agbagbe itan Işẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ ku işẹ o.

OLOTU

# IWE SI OLOTU

## Igboora nfẹ Ero–Omi

Olotu, Inu iba dun sẹṣe ti ẹ ba le gba mi laye lati le kesi awon Alaṣẹ Ilọba Ibile Igboora Igbimo wipe ki won se agbara lati kesi Ijọba ipinle Iwọ Orun Naijiria, ki nwọn le se Ero-Omi mimu fun wa ninu Ilu Igboora.

Ṣe bi ẹyin Igbimọ wa mọ gbogbo wahala nla ti awon Omọ Ilu yi nse lati le ri omi mu larin inu yi.

Ohun ti o tọ ti O yẹ fun Igbimọ ilu si wipe ki e tete se agbara fun ilu si lati le ri Omi ero ki asiko Ojo miran to de Owọ nyin yio maa roke o, Olotu.

Emi ni
BUSARI ALAWODE
Igboora.

## Iṣẹ nla ni Ogbẹni Yemitan Ṣe

Olotu, Iba dun mọ mi sẹṣe ti ẹ ba le te Iwe mi yi ja e ninu iwe Irohin nyin Aladun yi lati le fi ki Ogbeni Oladipọ Yemitan, fun iṣẹ nla ti o ṣe nipa kikọ iwe Ijala fun wa lati le maa ka.

Kin nsọ otitọ, emi a maa gbọ ti awọn Yoruba ma nsọ pe oriṣ kan wa ti awọn ọdẹ maa nkọ ti awọn pe ni Ijala.

Ṣugbọn nko tilẹ ti gbọri afi igbati mo ra iwe yi ti mo bẹrẹ si ka. O wa da bi enipe mo joko ti Olotu Iwe na ni ọjọ ti nkọ iwe rẹ.

Ẹ ku iṣẹ na o. Oluwa yio ran yin lọwọ.

Emi ni,
GEBRIEL LABEJỌ
Jos

## Ẹba wa tan Ina Ilu Gbọngan

Olotu, Ẹjọwọ gba mi laye ninu iwe Irohin nyin aladun yi lati le kesi awọn alaṣẹ Ijọ a Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria pe ki nwọn jọwọ ba tan ina lẹntiriki ilu Gbogan laipẹyi.

Ọsa tito 11 ọdun meji ti nwọn ti alẹ ina lẹntiriki na sarin ilu yi ti o fi da bi ẹnipe were ni nwọn o tan ina na.

Bi ina yi ba ti jẹ titan Ijọba yio ti mọ iye owo ti awọn na yio ti ko jọ ninu rẹ.

Mo ni ireti pe ẹ o ni gbagbe wao Mo dupẹ lọwọ nyin olotu.

Emi ni
B. BỌLADE
Gbọngban

## Ẹ moju to awọn Malu Apapa

Olotu, Inu mi yio dun ti ẹ ba le gba mi laye ninu Iwe Irohin nyin akọmolede lati le ba awọn ti nfa Malu larin ilu Apapa wa si Eko Shomolu ati Mushin sọrọ.

Iwa ti awọn ti maa fa malu yi nhu buru pupọ to bẹ ge e ti nwọn ki ifi jẹ ki awọn oni moto ati awọn oni kẹkẹ rin kọja ....

Iru iwa yi nfẹ amojuto gidi ki o ma ba da ede aiyede si'lẹ.

Mo dupẹ lọwọ nyin Olotu fun aye ti ẹ gba ni yi.

Ọkọ Oba ko ni ṣa nyin lese o.

Emi ni.
SALAMI ALADE
Apapa.

## Awọn Ole Pọ Ni Idi–Araba

Olotu, Inu mi yio dun ti ẹ ba le tẹ Iwe mi yi jade ninu Iwe Irohin nyin Oloyin momọ yi.

Mo fẹ ki awọn Ọlọpa wa gbawa lọwọ awọn Igara Ọlọsa ti nyọ wa lẹnu ladugbo wa Idi Araba.

Iwa awọn Ọlọsa yi buru ju epe lọ nwọn ko tilẹ bikita fun ẹnikẹni rara ati Ọsan ati Oru ni nwọn si njale.

Ohun ti o yẹ wipe ki awọn Ọlọpa maa wa ba wa bẹ Adugbo yi wo ki asiko Ọjọ to de, ti nwọn ba ri Ọlọpa, nwọn o dinku nwọn o si ma bẹru.

Mo dupẹ lọwọ nyin Olotu fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
ALFA BUARI OLA
Idi-Araba.

## Ikire Nfẹ Ina Lẹntiriki

Olotu, inu mi yio dun ti ẹ ba le gba mi laye ninu Iwe Irohin nyin oloyinmomo yi lati le ke si Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ohun ti mo fẹ ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun na ṣe ni pe o yẹ ki nwọn ṣe Ina Lẹntiriki si ilu Ikire titi de Apomu.

Bi ẹ ba ti le ṣe ina ju yio je anfani fun ilu wa awa na yio si ni anfani ti awọn ilu miran ni Ipinle yi ti ni.

Ẹ jọwọ e maṣe gbagbe gbogbo ileri ti ẹ ti ṣe fun wa lati ọjọ yi wa o.

Olotu mo dupẹ lọwọ nyin.

Emi ni.
SULE ABDUL.
Apomu.


## Akiyesi Pataki

A nfẹ Asoju ni awọn ilu wonyi, Otta Abẹokuta, Ibadan, Ilugun, Ololo, Agbowa,-Iko si Ikorodu, Ọyọ, Awẹ, Ilesha, Ẹde, Ikirun, Iwo Shaki Iṣẹyin, Tede, Oke-Amu, Iganna, Omu-Aran Ilorin Ajaṣẹ-Ipo, Ifọ, Abalabi, Idọgọ.

Kọwe si
Circulation Manager,
16, Gbamgbose Street,
Lagos.



E ... BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi iṣẹ rẹ tabi orisirisi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

## IWE Igbeyawo

TETE KOWESI ILE—ISE ERO—ITEWE
**Modupẹ Printing Press**
16 Gbamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.

KETEKETE NI ERO ITEWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NBGA

IROHIN KO TO AFOJUBA
Dawọ wa lọkanjọṣọ ki o si ri iyalọ



## AKIYESI

FUN IWADI, ITUMỌ ALA ATI IṢORO RẸ WA TABI KI O KỌWE SI: —WOLI ORIOLOWO AKINDELE ADEAGA COMPOUND ILE—ILUGUN VIA—IBADAN



BERE OJ... O EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN PE NI- Eleyi yato patapata si awọn

# RICHELET

Robi-robi. Iṣẹ rẹ lara ẹjẹ ni si daju fun iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA ni Mọnmọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Mọji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kak ri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ile yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ọjulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati awọn Iatambelu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru iaya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo ile tọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Ṣa dan go rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu.

Waterloon Mdicine Stores
8 Falmshurch Street, Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# Ijọba Ti Le Awọn Obinrin Kuro Ni Ararọmi

MUSHIN:- Pagidari igi nda ni ọrọ da ni ọjọ ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi bi awọn osiṣẹ ijọba ibilẹ mushin (Mushin District Council) ti bẹrẹ si wo awọn isọ ti o wa ni ọjọ Ararọmi.

Onirohin wa fi ye wa wi pe, bi ẹlẹmi ti nsa fun ẹmi te bẹni awọn ọlọja ng mura lati le ko ọja wọn pelu owo wọn ki o ma ba sofo

Onirohin wa tun fi ye wa wipe ohun ti o fa ti Igbimọ ibilẹ Mushin fi ṣe eyi ni pe, nwọn ki awọn ti ngna ọja yi ko lọ si ọja ti tun ti o wa ni opopo Ogunmokun ni.

A si tun gbọ wipe o ti le ni ọdun meji ti nwọn ti pari iṣẹ arin ọja titun na ti nwọn si ti kesi awọn ọlọja yi lati ko lọ si bẹ.

Akọwe Agba kan ni ile iṣẹ igbimọ Ijọba Ibilẹ Mushin fi ye Onirohin wa wipe lati osu meta sẹhin ni awọn ti akilọ fun awọn ọlọja yi lati kuro ni ọja Ararọmi ti nwọn ko si gba rara.

Nigbati ọrọ na su wa ni a ba fi agbara le wọn kuro ninu ọja na wipe, bi ẹ ko ba fẹ kuro ni erọ ẹo kuro nibẹ ni tipatipa.

Cbogbo awọn obirin Ọlọja na si ti kuro ni ọja Ararọmi nisisiy lọ si ọja Ogunmokun titun, ṣugbọn a ko ti mọ ohun ti Ijọba Mushin fẹ fi ọja Ararọmi ṣe bayi, ṣugbọn nwọn ko jẹki ẹnikẹni na ọja nibẹ mọ.

## ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARIUS Jan 20 - Feb 18) Gbogbo ohun ti o ba dawọle loni rere ni yio yọrisi, tọju iwa rẹ.

PISCES (Feb 19 - March 20) Maṣe tan ara arẹ jẹ, ohunkohun ti o ba nṣe loni, o nbọ wa jere rẹ lọla iba se rere, iba ṣe buburu, si gbiyanju lati ṣe iṣẹ ti o ti pati.

ARIES (March 21 - April 19) Ṣe pẹlẹpẹlẹ loni ki o si ṣọra, bi ara rẹ yio ti maa ya lati ṣiṣẹ bẹni ibinu kan wa niwaju rẹ, ṣọra gidigidi ki o ma ba ṣe siwahu.

TAURUS (April 20-May 20) Ọjọ oni dara fun ọ o si ṣe owo asejere ti o ko ba hu iwa aigbọran.

CANCER June 22 – July 22) Maṣe fi ara rẹ wewu loni tọju ara rẹ nitori aisan ojiji si ṣe pẹlẹ pẹlu ọrọ ija bẹni ki o si ṣọra rẹ pẹlu ọtọ asọju loni.

LEO (July 23 - Aug 22) Ti o ba ngiṣẹ ara rẹ owo aṣejere wa fun ọ loni, gbogbo idawọle rẹ rere ni yio yọrisi mura si iṣẹ ara rẹ, atẹlẹwọ ẹni ki tan ni jẹ.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Ọjọ oni dara fun ọ lati ṣe ibẹwo awọn ọrẹ ati ojulumọ rẹ ti o jinna si ọ. O ri iwe kan gba ti yio mu inu rẹ dun. Maṣe jiyan cara loni.

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Gbogbo ohun ti o ba nṣe loni ni inu yio ma bi ọ si, gbogbo ohun ti o dara pẹlu ki yio tẹ ọ lọrun, ṣugbọ awọn iṣẹ rẹ yio yọrisi rere.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22( Maṣe binu si awọn ohun ti o ti ṣe ni ọjọ pipẹ ti o ba wa si iranti rẹ, si gbiyanju lati san gbese ti o ba jẹ fun awọn olowo, iwa palapala kiṣe ẹran ajagbe.

SAGITTARIUS (Nov 23 – Dec 21) Ọjọ oni dara fun ọ, ohun gbogbo ti o ba si ngbero ni rere ni yio ma ri fun ọ. Bi o ba le ba olufẹ rẹ tage loni wẹriwẹ o wẹ.

CAPRICORN (Dec 22 – Jan 19) Gbogbo awọn ohun idiwọ ti o wa loju ọna rẹ ni ipa yio ka loni, ṣugbọn ṣọra nitori arẹ ojiji. Gbiyanju lati simi daada.

## E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ


## PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara [gidigidi fun "Spare" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigba kugba Alefọ. Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ adasin egbo, ekusẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara sisu Akọ Ioarun ati orişirişi arun "ARA" miran gbogbo.




Gbiyanju lati dan egbogi titun ti awọn ara Ilu Tatambulu ṣe ti wọn npe ni "PAYAL" wo larin ọjọ meta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu Egbogi ipara yi ki ṣe awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si ṣiṣe ye meji ninu lo jẹ eleyi si yatọ patapata si awọn ẹgẹrẹmiti adimowọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ere abgbi eko gbogbo ẹlu Orisi meji rẹ lo wa Kokere ati nla

Bere egbogi ajebinn Payal yi ni ṣọbu wọnyi:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)
(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street Yaba

## A TUN GBE DE!

Iwe Adura pataki fun Arisiki ati işẹgun rlio ohun gbogbo lati ilẹ Misirat, 2/6 Adura akanşe ati apẹrẹ ile aiye 2/- Ajọmọ-isin Ojişẹnla Mahammed 2/- Iwe Itumọ Ala ati Adura Ala ibanujẹ 4/6-

RANṢẸ TIRẸ SI:-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
Idumagbo Avenue Lagos Nigeria

AH! REMEMBER THAT

## The Social Dandies

*PRESENTS*

## An Eid–Ul–Kabir Dance

AT

FORESTFR CENTENARY HALL

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Odun Ileya) at 6 p. m. till dawn.

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, sieze this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E. Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recoring Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing,

**Tickets: 4/- Flat**

Tikets now on sale at 3, Olușhi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Offices. Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta,

# Iyatọ To Wa Larin Aawẹ Onigbagbọ Ati Imọle

Lati ọwọ E. A. AIYEGBAJEJẸ

Ki nto bẹrẹ ọrọ mi mọ kọkọ ki gbogbo ẹnyin ọmọ iya mi ninu Jesu pe ki Ore ọfẹ Jesu Kristi ki o mọ ba gbogbo wa gbe lai ati lailai amin. Pataki ọrọ mi ni iyatọ ti o wa ninu aawẹ ti awọn Onigbagbọ ngba ati eyiti awọn Onimọle ngba. Nitoripe ọpọlọpọ ko mọ wipe awọn Onigbagbọ gba aawẹ rara inu ọrọ mi yi ni ẹ fi mọ pe awọn Onigbagbọ ngbawẹ.

Aawẹ ti awọn Onigbagbọ yatọ si ti Imole, Ọlọrun sọ fun wa nipa aawẹ gbigba ti a ba wo "Isaiah 58:5-9 iwe Daniel 5 ẹsẹ kẹta Matthew 6:16-18.

Bi awọn Onigbagbọ ba ngba aawẹ ti wọn, nwọn ki jẹ saari ni afẹmọjumọ bi ti awọn Imọle, onjẹ ti a ba jẹ ni alẹ ni a nilati fi gba aawẹ o jẹ odidi wakati mẹrinlelogun eyi ni aawẹ ti inu Ọlọrun dun si ti o si tun tọna pẹlu papapa awọn Onimọle ti o mọ Kurani dada le jẹri si ọrọ na pẹlu Aawẹ ti awọn Onigbagbọ ni o njẹ lẹnti.

Ipari Awẹ ti wa ni a mọ ṣe ọdun Ajinde ti Jesu Kristi Oluwa ati Olugbala wa. Angba aawẹ gẹgẹbi ilana ti Jesu Kristi fi kọ wa ninu Bibeli nigbati o sọ wipe ti a ba ngbawẹ ki a mọ ṣe bi awọn kan tabi agabagebe ti nwọn ba ngbawẹ ti nwọn mọ polongo pe awọn ngbawẹ o ati bẹbẹ lọ. Ewo inu Bibeli Matthew 6:16-18.

Bi a ba kiyesi awọn alufa ti o mọ ngba aawẹ arugbo awọn gan ni ontẹle ilana aawẹ nwọn ko ni mọ polonwo kiri pe aawẹ ngbo mi o ati bẹbẹ lọ.

Asiko ti awọn onigbagbọ ma gba aawẹ wọn ni ọjọ ke jila oṣu keji ọdun ni ọdọdun ki ore ọfẹ Olodumare ma ba wa gbe.

Ẹmẹta ni awọn Imale ma jẹun, nwọn yio jẹ Saari nwọn yio tu ẹnu, nwọn yio tun jẹ onjẹ alẹ. Ṣe ẹ ri pe o di ẹmẹta, ṣugbọn ti awọn onigbagbọ onjẹ alẹ nikan ni ko si a nfa oju ro nitoripe a ngba aawẹ.

Oluwa ko kọ wa ki a ma pariwo pe, aawẹ ngbomimo ngbawẹ rara bi ẹ ba ri awọn onigbagbọ ẹ ko ni mọ pe nwọn ngbawẹ.

## Ishọla Jale Ṣile Mẹwa, O Wẹwọn Ọdun Mẹrin.

YABA:- Kẹkẹ pa mọ gbogbo awọn ero ti o wa woran ni le ẹjọ kotu kan ni Yaba lẹnu bi Adajọ kotu na ti da ẹwọn ọdun mẹrin fun ọdaran kan Ishọla.

Ẹsun ti awọn ọlọpa fi kan Isọla nipe o fi ọgbọn ẹwẹ jale sile mẹwa (10/-) ninu apo ọgbẹni Morakinyọ Alafẹ ni ọja Oyingbo ni ọjọ kẹwa osu kẹta ọdun ti o kọja yi.

Ninu idajọ rẹ adajọ kotu na fi han pe, nitotọ ni on ri pe orisirisi iwa buburu pọ lọwọ awọn ọmọ jaguda Iru Iwa ba yi lo fa ti Isọla fi hu iru iwa bu uru yi.

O ni on gba wipe bi ijọba ko ba mura lati fi opin si iru iwa wọnyi ohun buburu yi nwọn yio jẹ abuku fun orilẹ-ede wa Naijiria.

O wa paṣẹ pe ki o lọ fi ẹwọn ọdun mẹrin jura.


## AKARA TU S'EPO !
**Iwe Itumọ Ala na ti de !!**



Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumo Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pẹlu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

J. O. SHOYINKA
N2/99 Shittu Street
Ibadan

## EGBOGI JẸDIJẸDI



**"CYCLEVEN"**

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jedijedi rẹ gbe wa lara rẹ o si nyọ o lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbonse. Arun Jedijedi je ọkan ninu amod ti o buru ni pataki fun Okunrin si o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpolọpọ egbogi ni awọn kakiri lode nisiyi ti wọn a ma powo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara, Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bere bakana. Orisirisi Jedijedi ni o wa ekini ti o bere nipa aiko ma pe igbonse dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna ṣelu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupoju nigbakugba. Jedijedi orisirisi ni o wa, ewo ni tiẹ? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba ninu ẹ wa lẹhin igbonse, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbonṣẹ tan ni, tabi ti o ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ ko ki o si danwo orisi mẹta ni o dajụ wipe iwọ yio bọ lọwọ Jedi patapata ati pe yio de si ẹleji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi ṣe igbonse ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 560 FRIDAY MARCH 20, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni ongbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16 BA MGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.

# Awọn Aja Mẹfa Yege Idanwo Iṣẹ Ọlọpa

EKO:— Laipẹyi ni awọn Aja mẹfa tun pari ẹkọ wọn gẹgẹbi iṣẹ ọlọpa ti nwọn si kọ wọn ti nwọn ṣe daada ninu iṣẹ wọn na. Ni opopo Keffi ni Obalende ni awọn Aja na ti nkọ iṣẹ wọn pẹlu awọn enia mẹfa ti yio ma mu wọn lọwọ kiri.

Irohin Ijọba sọ fun wa pe, nwọn ti gbe awọn Aja na lọ si teṣan ti nwọn yio ti bẹrẹ iṣẹ wọn.

Awọn Aja yio lọ bẹrẹ iṣẹ wọn ni ọgba ọkọ-ilẹ (Nigeria Railway) lati ma rin kakiri gbogbo ile ti nwọn ko awọn ẹru ati awọn iṣura si. Nwọn yio ma mu oju to gbogbo ọgba to yi ọkọ-ilẹ na ka pẹlu awọn to mu wọn kiri, gbogbo ile-Ijọba ti awọn enia ngbe, ati ile iṣẹ ni awọn Aja yi yio ma kiri.

Ki awọn Aja to nṣe Ọlọpa to kuro ni ile ẹkọ wọn ni awọn Aja yi ati awọn ti nmu wọn lọwọ ni Olori Ọlọpa agba fun ilu Eko Ọlọla M. E. K. Roberts si yin awọn Aja na ati awọn ti o nfa wọn lọwọ fun ọna ti wọn ngba fi nṣe iṣẹ ra

Irohin tun fi ye wa pe, awọn Aja mẹrin tun wa ni ile Ẹkọ na ti nwọn nkọṣẹ ọlọpa lọwọ.

Laipẹ ni onirohin wa kan sọ pe, awọn Aja kan ti wa ti nṣe iṣẹ ọlọpa, to jẹ pe, nwọn mọ ole mu daada ju ọlọpa alara lọ. Bi enia ko ẹru ẹlẹru si iho imu nwọn yio wa ri.


TRADITION REFLECTED IN PROGRESS

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ or RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.


## Ọmọde Kan Ku Sinu Odo—Ọsa

APAPA:— Ah, ṣe gbogbo enia nigbati awọn Oṣiṣẹ ati awọn ero nlọ ni deede agogo meji Ọsan ana Ọjọ Ọjọ' Bọ ti iṣe Ọjọ kọkandinlogun Oṣu yi ti nwọn ri oku Ọmọde kan ti o lefo ni Oju Omi Odo—Ọsa.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia na ba ranṣẹ si awọn Ọlọpa lati wa wo ohun iyanu na

Nigbati awọn Ọlọpa ri iṣẹ na gba, were ni nwọn ti gbe mọto wọn de ti nwọn si ri oku ọmọde na loju odo.

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ba sare bọ sinu odo, ti nwọn si gbe oku ọmọde na jade.

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa wipe, ọmọ ọdun meji pere ni ọmọ na, nwọn ko si mọ ohun ti o ṣe e ki o to ku sinu odo ọsa ṣugbọn nwọn ti gbe oku re lọ si Ile iwosan Lakulaku fun ayẹwo.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495 one 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) Bariga Yaba Lagos (20/3/64)